Iwe Irohin gbogbo Onigbagbọ
**IKEDE IṢẸ OLUWA**
a ma jade ni ọjọjọ Thursday. Fi stamp kọbọ meji ranṣẹ si Olotu, P.O. Box 69, Mushin, Lagos.

# Irohin Yoruba

No. 802 | OCTOBER 19 — OCTOBER 25, 1960 | Kobo Meji (2D.)



Jẹ egbogi ti o daraju fun ọmọde
O wa fun tita kakiri ile-egbogi

# ALAKE BA AWỌN IMALE ẸGBA SỌRỌ

## O ni gbogbo awọn enia gbọdọ wa ni irẹpọ, ki nwọn si ṣe alekun iṣẹ, ki ominira yi le jẹ ti alafia ati if'aiyabalẹ fun gbogbo ilu.



*Ọlọla Ladapọ Ademọla Kẹji Ọba Alaiyeluwa Alake Abẹokuta*

AKE ABẸOKUTA

**Irohin ko to afojuba ni adura idupẹ ajọyọ gbigba ominira Ijọba Apapọ Naijiria ti gbogbo awọn Ijọ Musulumi igun mẹrẹrin Abẹokuta gbarajọ ṣe ni gbalasa ojude Afin Ake, Abẹokuta ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi.**

Ọlọla Ọba Alaiyeluwa Ladapọ Ademọla Kẹji, Alake Abẹokuta, ati awọn Ọba mẹrẹrin Abẹokuta yuku, Olowu, Agura Ọṣilẹ ati Olubara si wa nibi aṣẹyẹ adura idupẹ na pẹlu awọn enia jankan-jankan igun mẹrẹrin Abẹokuta ti o wa si ibi adura na.



OLOWU OWU

Ninu ọrọ ti Ọba Alake fi ki awọn Ijọ Musulumi na, o ni itumọ ominira jẹ alekun-iṣẹ fun gbogbo ara ilu ni gbogbo ayekaye ti ọmọ enia ngba a fi ṣiṣẹ. O si kesi gbogbo awọn enia Abẹokuta, lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati lagba, iba a jẹ Onigbagbọ, Imale tabi Aborisa pe, ki gbogbo nwọn fi ọwọ sowọpọ lati ṣiṣẹ ki nwọn si jẹki ominira titun ti a gba yi jẹ ti ayọ, alafia ati ifaiyabalẹ fun wa ati fun gbogbo enia ilẹ Naijiria.

Ọlọla Ọba Alake si tun fi gbogbo enia lọkan balẹ pe, "dajudaju, nipa ofin titun ti gbigba ominira na mu wa fun Abẹokuta nisisiyi, awọn Oyinbo Ajoji ati Oniṣowo yio tete fi eyi kọwọ lati wa da oriṣiriṣi iṣẹ silẹ ni ilu Abẹokuta, eyi yio si din airiṣẹ'ṣe ku fun awọn enia ni igboro ilu Abẹokuta".

### ILẸ GBIGBA

O ni nitori eyi, Ijọba yio nilati gba ilẹ pupọ si i lati fẹ ilu Abẹokuta siwaju si i, ki o si ni aye pupọ lati tubọ fẹ siwaju. O si bẹ gbogbo awọn enia ti nwọn jẹ onilẹ ni ilẹ Ẹgba ki nwọn ma a yọnda ilẹ wọn fun awọn oṣiṣẹ ati oniṣowo ajeji wọnyi ki airiṣẹ'ṣe ba a le dinku ni ilu Ẹgba.

Ninu ọrọ ti awọn Ijọ Musulumi Ẹgba fi ki gbogbo enia ilu Ẹgba ku-orire fun gbigba Ominira Ijọba Apapọ Naijiria ni nwọn gbe tẹnumọ ọrọ ilọsiwaju ẹko fun awọn ọmọ Imale ati itankalẹ ẹsin Islam. Nwọn si bẹ gbogbo Musulumi Abẹokuta pe ki nwọn tubọ ṣe iranlọwọ owo-dida fun Mọṣalaṣi Jimọ Abẹokuta, ki nwọn si pese Ile-ẹko giga fun awọn ọmọ Musulumi lọkunrin ati lobirin, ki nwọn si da



IBRAHIM DENDE
Olori emọmu Ẹgba

ile-iwe silẹ lati ma a kọ awọn olukọ ni ẹkọ kewu-Larubawa.

Nigbati Alhaji D. S. Adegbenro, Minista Alamojuto Eto Ijọba Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun nfesi ọrọ awọn Ijọ Musulumi na ni orukọ awọn aṣiwaju ilu Ẹgba, o ki Ọba Alake kuorire fun gbigba Ominira Apapọ Ijọba Naijiria ti o ṣoju ẹmi rẹ, eyiti on ati ọpọlọpọ awọn aṣiwaju ilu Ẹgba ti nja fun lati ọpọlọpọ ọdun sẹhin.

Ẹsẹ gbogbo ọmọ Ẹgba ni'le, l'oko ati lati ilu okeere lo pe sibi adura ominira na. Eto ọjọ na bẹrẹ pẹlu adura kekere ti Alhadji A. M. Ahmad ṣe. Lẹhinna ni Oloye Alfa Shittu arọwasi Ẹgba ṣe adura nla pẹlu Alhaji A. R. Akorede ati awọn ijọ rẹ.

Eto ọjọ na pari pẹlu adura aṣẹkẹhin ti Olori Lemọmu Abẹokuta, Imam Ibrahim Dende.

Ninu awọn enia jankan-jan-kan ti wọn wa sibi adura nla yi ni Alhadji D. S. Adegbenro, Ọlọla Alhadji A. L. Adelẹkan, Alhadji L. O. Bello, Ọlọla Adeniyi Adedamọla.

(Wo oju ewe kejila)



ALHAJI D S ADEGBENRO

# Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ikilọ fun awọn Agbẹ

## "Ẹ ma ṣe fun ẹnikẹni ni owo ẹhin lati ya owo ...."

OGBENI L. G. K. Ogunwolu, alakojọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Iha Ila-Orun Ẹgba ṣe ikede ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu kẹsan ọdun yi pe irohin ti kan Ẹgbẹ Afẹnifẹre wipe awọn enia kan ti da ẹgbẹ kan silẹ ti nwọn npe ni "Ẹgbẹ Oluranlọwọ Agbẹ". O ni awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti si gbọ wipe awọn enia kan ngba silẹ mẹta-mẹta lọwọ awọn enia kakiri arọko, ti nwọn si nṣe ileri fun awọn ara arọko yi pe awọn yio ṣe iranlọwọ fun wọn nipa yiya wọn lowo.

Eyi ni ikilọ ti Ọgbẹni Ogunwọlu ṣe nipa awọn ẹgbẹ yi:—

"Ẹgbẹ Afẹnifẹre nfi iwe yi sọ fun gbogbo awọn enia wipe nwọn ko ni ọwọ ninu ẹgbẹ na, ati wipe ẹnikẹni ti awọn ẹgbẹ yi ba fi ogbọn ẹtan gba owo yi lọwọ rẹ, bi ko ba ri owo gba lọwọ wọn, ki o maṣe fi ọrọ na sun Ẹgbẹ Afẹnifẹre nitoripe ẹnikan ko ran oluwarẹ nisẹ. O yẹ ki o han fun gbogbo awọn agbẹ wipe ko si ẹgbẹ kankan ti o le ṣe iranlọwọ fun awọn agbẹ ju Ẹgbẹ Afẹnifẹre lọ.

### Ẹ LỌ RI AKỌWE

"Ẹgbẹ ti o ba nfẹ iranlọwọ nipa yiya owo, ki o wa si Owode lodọ Akọwe Lonu (Loan Secretary) lati wa gba iwe ti nwọn yio kọ fi ranṣẹ nipa owo yiya.

"Bi nwọn ko ba tete dahun ki ẹnikẹni ti o ba nfẹ ya owo lọ ri akowe ẹgbẹ Ọlọla J. F. Ọtẹshile tabi Igbakeji Alaga Ẹgbẹ Ọlọla J. A. O. Ṣobọla on ni yio ṣe iranlọwọ lati gba owo laigba kọbọ owo ẹhin lọwọ agbẹ kan.

"Ṣugbọn a fẹ ki ẹ ranti wipe ki iṣe gbogbo wa ti o ba gba iwe (Form) na ni o le ri owo gba lẹẹkanna tan, diẹ-diẹ nibẹ ni o maa fi ri i gba.

"Ẹnikẹni ti nwọn ba bere owo ẹhin lọwọ rẹ, iba jẹ Kansilọ tabi ẹnikẹni ni Ẹgba, ki ẹ maṣe bẹru lati lọ fi ẹjọ rẹ sun awọn Oloye Ẹgbẹ ti mo kọ orukọ wọn si isalẹ yi pẹlu ẹri ti o daju.

### AWỌN OLOYE ẸGBẸ

Oloye J. S. Lajiga, Baba Ẹgbẹ, Ṣiwun.

Oloye Olusọji Allen-Taylor, Igbakeji Baba ẹgbẹ, Ọba Oluwo.

Oloye A. O. Osanyinbi, Mowe.

Oloye Iyaafin Banjoko, Iya-ẹgbẹ, Owode.

Oloye Iyaafin Safuratu Sanusi, Igbakeji Iya-ẹgbẹ Ọfada.

Oloye Ayọ Roṣiji, Alaga Ẹgbẹ, Eko.

Ọlọla J. A. O. Ṣobọla, Igbakeji Alaga Ẹgbẹ Owode

Ọlọla J. F. Ọtẹṣile, Akọwe-ẹgbẹ, Owode.



OLOYE AYỌ ROṢIJI

Ọlọla I Oke Ogundipẹ, Igbakeji Akọwe Ẹgbẹ, Abẹokuta.

Ọlọla E. I. George, Akapo Ẹgbẹ Ṣiwun.

Oloye Daniel Ladele, Boto.

Ọlọla T. B. Osibọ-Ọlabiede, Oluye Owo Ẹgbẹ wo, Ọfada.

"Ẹnikẹni ti ẹ ba ri ninu awọn oloye ẹgbẹ ti orukọ nwọn wa ni oke iwe yi ni ẹ le lọ ba, bi nwọn ko ba tete da nyin lohun lati gba iwe na, nigbati o ba wa nile.

Wo oju ewe kẹdogun


## Ẹbun Ilera



Ara-lile, agbara ati okun-inu ni iṣura ti o koja idiyele, awọn ẹbun ẹda ti o dara julọ ni. Ko si onjẹ miran ti o nfun ni l'okun-ilera atata bi Ovaltine, ohun ti a fi peelo rẹ ni onjẹ atẹjẹẹe ati eyi ti o nfun ara ni okun. Mimu Ovaltine lojojumọ ni ọna ti o dara julọ ti o si rọrun julọ lati fun ni ni ọpọlọpọ ilera ti o dara tẹlẹ, lati ri i daju pe a ni okun lojojumọ ati idẹra, orun asun-wọra. Ẹgbẹgbẹrun awọn ọlọmode ni nwọn mọ anfani atata ti Ovaltine ni, onjẹ olomi ti o dara julọ ni.

OVALTINE






## Nihin ni IRORA rẹ wa

*Iwe aworan yi ni o fi ibiti aisan gbe wa lara han nigbati awọn erẹẹ inu rẹ ko ba ṣiṣẹ deede*



# DeWitt's

**Kidney & Bladder Pills**

nṣe iṣẹ afunnjẹ eree inu taara ni lati ti ere inu ti o ngmu irora wa jade

Lẹhin wakati diẹ ti o ba ti lo "De Witt's Pills" tan itọ rẹ yio mu awọ miran wa. Eyi ni ẹri pe oogun ti o yanilẹnu yi ti bẹrẹ si ṣiṣẹ niyẹn, o nda LAKUREGBE, ARA-RIRO, ẸHIN-DIDUN ATI GBOGBO IYỌNU APO-ITỌ DURO



# DeWitt's

**Kidney & Bladder Pills**

# Irohin Yoruba
# ORO OLOTU

## ESI TAFAWA BALEWA L'A NRETI

NINU isipaya ọrọ alaye ti a sọ ni ọsẹ ti o kọja lori pe "Bi Ipinlẹ ba bajẹ kini olododo yio ṣe?" A mu itan Rehoboamu ọmọ Sọlomọnu ti o jẹ Ọba tisun lẹhin ti baba rẹ ku ṣe apẹrẹ bi awọn agbaagba Israeli ti ṣe wa si ọdọ rẹ ti nwọn nfẹ gbọ lati ẹnu rẹ bi yio ti ṣe ṣe e ti eto ijọba rẹ yio fi rọ awọn lọrun ju ti baba rẹ lọ.

ṢUGBỌN dipo ki o gba ọgbọn awọn oselu ti nwọn ni lakaye bi ọba ti ṣe le jẹ ọba alafia fun awọn ara ilu ki o to ri awọn ara ilu na mu sin, ko gba iyẹn, ti awọn apẹrẹ ti nwọn jijọ dagba pọ ni o gba, on si lero pe ti on ba gba imọran awọn agbaagba, awọn ara ilu yio sọ pe on ko ni aiya to lati jọba le awọn lori, ṣugbọn bi on ba gba imọran awọn ipẹrẹ yi lọ, nwọn a mọ wipe on yio ṣe ju baba on Sọlomọnu lọ.

NISISIYI, gbogbo awọn olugbe Naijiria nsọ fun Alhaji Tafawa Balewa ajaga ti awọn ti ngbe ni abẹ Ijọba Gẹẹsi ni awọn lara awọn si nfẹ bi yio ti ṣe jẹ pe Ominira Ijọba wa ti kuro ni abẹ ajaga na. Njẹ ajaga Ominira Apapọ Naijiria ki yio wa ṣọrun fun wa ju ti abẹ Ijọba Gẹẹsi lọ? O dabi orin awọn Onigbagbọ kan ti o kọ bayi pe:—

Idahun rẹ l'a nreti o
Idahun rẹ l'a nreti o
Gbogbo ẹda l'o dori ko'do
Idahun rẹ l'a nreti o.

GBOGBO Naijiria nreti idahun rẹ lori Ominira Naijiria pe, iru eto iṣelu wo ni ẹ fẹ ṣe ti gbogbo awọn yio ṣe mọ ọ lara ati ni ẹmi pe awọn gba ominira kuro labẹ Ijọba Gẹẹsi, tabi ti ajọyọ ominira ti a ṣe kọja nikan yi na ni adun ti o wa nibẹ?

LAIJẸPE a gbọ bi eto iṣelu Naijiria yio ti ri lati ẹnu Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria, a ko le ṣe alaye kikun fun awọn ara ilu pe iru idẹra ti a o ni niwọnyi ti a o fi mọ pe a bọ sinu Ominira Ijọba tiwa. Nitori "a ki i gbọn ju bi ngo ti ṣe nkan mi re e lọ." Ijọba Apapọ Naijiria ti di tiwa "iṣu wa lọwọ wa, ọbẹ wa lọwọ wa". Awa ni a yan awọn aṣoju sibẹ lati ma a ba wa ṣe eto idẹra wa ni Naijiria bi yio ti ṣe ṣọrun fun wa.

YORUBA ni si ma a pa a lowe pe, "Nṣe ni a pegbọn a ki i pe ẹ gọ. Ika wo, Iwori wo o, ohun ti a ba jọ wo gigun ni i gun", nitori bẹ ẹ ni awọn olugbe Naijiria ṣe yan ẹnyin ọjọgbọn oselu onilakaye lati inu awọn ilu Naijiria kakiri pe ki a wariko lati ma a fi eto iṣelu nyin wa alafia fun gbogbo wa, ki eyi si jẹ ohun ti awa paapa yio fi gbadun ki a si ma a kan-saara si nyin.

## Si awọn onibere ala

OLOTU, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati sọ fun awọn ti o mbere itumọ ala wọn lọwọ mi pe, nko fẹ ki awọn onibere nu ma a bere ju itumọ ala kanṣoṣo lẹẹkan lọ. Ogunlọgọ enia ni nfẹ mọ itumọ ala wọn, aye ko si ni si bi a ba nte ju itumọ ala kanṣoṣo lọ. Mo si bẹ ẹnyin onibere na lati ma a kọ ibere nyin yanju nitori ati tete ba ma dahun wọn.

Emi ni,
JOSẸFU ALALA.
Mushin.

## A nfẹ itan Ikire

INU mi yio dun bi Olotu ba le yọnda fun mi lati kesi awọn ti nwọn mọ itan ilu Ikire lati kọ itan ilu na sọwọ si Olotu Iwe "Irohin Yoruba" fun titẹ jade fun anfani awa onkawe ati ọmọ Ikare nitoripe itan ọpọlọpọ ilu ni a nri ka ninu iwe na, ṣugbọn a ko ri ti ilu wa ka. E jọwọ o, ẹnyin opitan, ẹ ba wa pa itan ilu wa na o.

Emi ni,
M. A. OLUTUNBI
Oke-Aiyedun-Ekiti.

## A nfẹ mọ itan ilu Ọtta

MBA ṣọpẹ lọpọlọpọ bi Olotu ba le fun mi laye ninu iwe "Irohin Yoruba" lati kesi awọn agbalagba ati awọn opitan ilu Ọtta lati sọ itan ile Otta ninu iwe "Irohin Yoruba" fun kika gbogbo wa. Nitori ọpọlọpọ itan ilu ilẹ Yoruba ni a mi ka, ilu ilẹ Yoruba ni a nri ka, rara.

Emi ni,
A. A. ADEORIJO
Zaria.

# Iwe si Olotu Irohin Yoruba

## Imọran fun awọn Ọlọja Eko

ATI ṣe ajọyọ Ominira Naijiria kọja bi o ti lọ ati bi o ti yẹ. Gbogbo awọn adugbo ati ile-ọja kọ ni Ijọba tunṣe daradara, de aye ti gbogbo awọn alejo ti nwọn wa fun ajọyọ ominira na ko ri nkan abuku kan rara.

Mo bẹ awọn ọlọja Ereko lọtun losi, mo bẹ awọn ọlọja Ita Faji, mo si bẹ awọn ọlọja Jankara atijọ ati ti aṣẹko yi ki nwọn maṣe ṣe ohun ẹgbin kan sinu tabi lẹba tabi yika ọja wọn mọ nitoripe irufẹ nkan bẹ ẹ i ma a fa aisan si enia, i si ma a ko abuku ba ilu ni.

Emi ni,
ALHADJI Y. A. DISU.
Eko.

## Mo dupẹ lọwọ Ijọba Afẹnifẹre

INU mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati dupẹ lọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fun ọda ti nwọn da si ori titi ti o la ilu Iragbiji kọja. Ṣugbọn a bẹ Ijọba na ki nwọn ba wa ṣe omi-ẹrọ si ilu wa na.

Mo dupẹ o.

Emi ni,
AṢIRU AWODIJI.
Iragbiji.



# Ọmọ-Ọba Alexandra ti pada lọ si ilu rẹ, o si dupẹ lọwọ gbogbo ara Naijiria















## AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọ ọ sọwọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdalẹ Yoruba. A o si tẹ ẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU

**Otutu fẹrẹ ti fun un ni "K.O.!"**



1. Nigbati o ku ọjọ meji lati ja ija na—Battling Sam bẹrẹsi wukọ o si ṣain.

2. Alabojuto rẹ ni: "Ogbẹni —a ni lati le otutu yen lọ ni" Sugbọn lọna wo? Lẹsẹkẹsẹ ni o ranti—Mentholatum

3. Lẹhinti o fi Mentholatum atura ati adẹra pa ara l'akọ-kọ. Sam bẹrẹsi gbadun. Nigbati o ku wakati diẹ ki o de agbo ni segun ija rẹ ti naro.

4. Ija nla na de. Battling Sam bẹ s'agbo bi amọtẹkun lati gbe onija rẹ ṣanlẹ lori ija karun. Gbogbo enia ho ṣee pe "Sam ọoku-tọọ" Sam ni "ọpẹlọpẹ Mentholatum" "Dajudaju o gbọn otutu mi nu.



Fi Mentholatum bọ imu rẹ—ki o si ma a mi pẹlu irọun. Fi diẹ pa aiya rẹ—ki o si fowọ ra a wọnu! Ikọ rẹ yio lọ laipẹ. Mentholatum atura ati adẹra ṣaiṣe bi idan ni nigbagbogbo! Menthoatum dara fun jẹdi-jẹdi, pẹlu —a tete mu itura wa! Ri i daju pe ojulowo Men-tho-lay-tum ti o wa ninu awọn ọangolo ati awọn idẹ gẹgẹbi awọn apẹrẹ wọn yi ti o bere fun. Maṣe ra awọn adamodi

Awọn nikan ti nwọn nṣe ni

**MENTHOLATUM CO. LTD**
(Est. 1889), Slough, England

**MENTHOLATUM**

**IPARA TI O DARAJU**

# Akiyesi awọn awo Irawọ nipa Ọjọ-Ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣẹlẹ larin ọsẹ yi.

## CAPRICORN
**(Dec. 21-Jan. 19)**

Iṣẹ rẹ yio dara, igbesi aiye rẹ yio si dun. Ki ọsẹ yi to pari, ire kan yio to ẹ lọwọ. Wa a ni iṣoro diẹ nipa ọran ẹbi tabi ti olufẹ rẹ atijọ.

## AQUARIUS
**(Jan. 20-Feb. 18)**

Ẹnikan yio fun ẹ ni imọran kan ti yio ṣe ẹ ni anfani 'nu ọdun titun ti mbọ Awọn nkan yio bọsi dada fun ẹ ju bi o ti ni ero si lọ. Wa a gbadun ọsẹ yi pupọ.

## PISCES
**(Feb. 19-Mar. 20)**

Irẹ yio ri iṣoro diẹ nipa ọran ẹbi tabi owo (money) iṣoro na yio si ka kuro ni ipari ọsẹ yi. Ọjọ Ẹti ati ọjọ Abamẹta yio ṣe ẹ ni anfani lati ṣe adehun pataki.

## ARIES
**(Mar. 21-Apr. 20)**

Iṣoro ti o ba ni nipa olufẹ yio bọ si irọrun. Gbogbo ero buburu ti awọn ara ile ba gba si ẹ ko ni ṣe ẹ ni nkankan rara, irẹ yio ma a ri igbega siwaju ati siwaju ni, ṣugbọn ṣe suru ati aanu.

## TAURUS
**(Apr. 21-May 20)**

Iṣoro diẹ yio ṣẹlẹ si ẹ lẹnu iṣẹ rẹ. Ọran ẹbi rẹ yio wa bọsi eto dada de aye ti yio fi yanju ni ipari ọsẹ yi.

## GEMINI
**(May 21-June 20)**

Titi ipari ọsẹ yi, irẹ yio ri asiki owo. Bi o ko ba ti ṣe igbeyawo, wa a ṣe e laipẹ ọjọ. Bi o ba si ti ṣe bẹ ẹ , igbega yio wa fun ẹ larin awọn ẹbi rẹ lẹnulọlọyi.

## CANCER
**(June 21-July 20)**

Maṣe damu bi alagba kan ba di ẹ lọwọ nipa eto kan ti o nṣe, ayipada fẹrẹ de na. Ọrẹ rẹ kan yio ran ọ lọwọ.

## LEO
**(July 21-Aug. 21)**

Ọrẹ rẹ kan yio ṣe ọna igbega fun ẹ, alejo titun kan yio si ran ẹ lọwọ bakanna. Maṣe ṣe iṣẹ agbara tabi iṣẹ ti o nira, ma si ṣe lo ara rẹ ni ilokulo.

## VIRGO
**(Aug. 22-Sept. 22)**

Ọran ọrẹ rẹ kan tabi ẹbi rẹ kan ndun ẹ lọkan gẹgẹbi iwa ti o hu si ẹ, ro ọran na fun igba diẹ ni. Owo yio to ẹ lọwọ ninu ọsẹ yi.

## LIBRA
**(Sept. 23-Oct. 23)**

Irẹ yio ṣe eto kan nipa owo (money) ati igbesi-aiye rẹ ni ọsẹ yi. Ede-aiye kan yio ṣẹlẹ larin awọn ẹbi rẹ.

(Wo oju ewe kejila)



*Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"*

# Awọn ọmọ ibilẹ Naijiria ni Ghana ṣe ajọyọ Ominira

SUHUM-GHANA.

GBOGBO ẹsẹ awọn ọmọ Naijiria ni o pe ṣọṣọ ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi fun ipade pataki kan lori ajọyọ Ominira Naijiria. Ibikan ti o gbaye pupọ ni nwọn pesi biba. Nibẹ ni nwọn gbe ti fi ohun ṣọkan lati ran Asia Ijọba Naijiria ati ti Ijọba Gẹẹsi lọtọọtọ fun lilo ni ọjọ keji ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kini oṣu yi, ọjọ Ominira Naijiria.

Gẹgẹbi ohun ti nwọn ti ri ka ninu iwe irohin, nwọn ṣe eto bi nwọn yio ti ṣe ta Asia Ominira Naijiria soke ati bi nwọn yio ti ṣe ka ti Ijọba Gẹẹsi wa silẹ ni ọjọ ti Naijiria di Ominira. Nigbati aseko na to, gbogbo wọn lo aso atata nwon si pe si ibikanna, nwọn si ṣe bẹ ẹ tayọ-tayọ. Nwon lo si ṣọọṣi lo gbadura, nwọn jo orișiriși ilu, nwọn si jẹ, nwon mu u.

Awọn Alufa Moses Ọla Arẹmu, Joseph Akanni, M. M. Oloyede, Joel Ọmọ Inisha ati Ọgbẹni Owolabi ṣe bẹbẹ ni ṣọọṣi, nwọn ṣiwaju ṣe isin alarinrin, nwọn si kọrin iyin Oluwa logo.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi nwọn tun lọ si ṣọọṣi lati ṣe isin idupẹ fun Olọrun, nwọn si kọ orin bakanna, nwọn yin Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre nwọn si ki i ku orire.

## *Arugbo meji ja ajadaku nitori epinni*

MUSHIN.

IROHIN ko to amojuba ni ija ti awọn arugbo obinrin meji ja ni Oju-Woye, Mushin, ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu kẹsan ọdun yi. Ọkan ninu awọn alajangbila na si daku finrin-finrin.

Ohun ti o da ija na silẹ ni ariyanjiyan nigbati iya arugbo kini ra ẹfọ lọwọ iya arugbo ẹlẹfọ keji. O ra oni kọbọ kan abọ, o si fun un ni kọbọ meji. Iya ẹlẹfọ fun arugbo oraja yi ni ṣenji epinni. Ṣugbọn o kọ epinni na, o ni owo na yọ.

Iya ẹlẹfọ ni on kọ ni o ṣe owo, Ijọba lo ni owo, nitorina on ko le parọ epinni na.

Inu bi iya arugbo keji yi awọn mejeji si bẹrẹsi ta ohun si ara wọn, lojiji ni nwọn lọ ara wọn mu ni papakoko, nibiti nwọn gbe ti nlu ara wọn, iya ẹlẹfọ ṣubu, o si daku patapata.

Ariwo ta, ẹsẹ awọn enia si ti pe sibẹ. Awọn ara adugbo ibẹ si ṣajo iya arugbo na pupọ.

Aya iya arugbo keji ja pupọ, ko mọ nkan ti o le ṣe, on na ba ṣubu lulẹ, lo ba ngbọn on, awọn tun ṣajo rẹ. Nigbati o ṣe ti oju iya ẹlẹfọ walẹ tan, ti on na si ri bi arugbo keji on ti nṣe, ko mọ nkan ti o le ṣe mọ. Ọpẹlọpẹ awọn enia ti nwọn wa ṣe ajo wọn, oku ko ba di meji lọjọ na.

Awọn enia ba mu awọn mejeji lọ si ibi ti olukuluku ngbe.

Iya to ra ẹfọ ko tilẹ tun ranti ko ẹfọ nilẹ mọ, iya arugbo keji paapa fi owo ẹfọ to gba silẹ nibi ti nwọn gbe ti ja.



Eni-owọ julọ Primate E. M. Olulode. Awọn ontẹwe wa ṣi orukọ rẹ kọ ninu iwe Irohin Yoruba ọsẹ ti o kọja. Aṣiṣe yi ṣe wa laanu pupọ.


ṢỌRA FUN

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro pẹlu

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

LAKUREGBE!

ALGESAL

*ti le e lọ*



ALGESAL jẹ itesiwaju iyanu fun igbogunti lakuregbe. O dara ju ti atẹhinwa lọ, o npa oro orike ara-giga ati ara riro. ALGESAL ni Dityist ninu asesewakan aporo tilun ti o nwọ inu iṣan-ara lọ ni, o si nyara tuka sinu iṣan-ẹjẹ. ALGESAL npetu ṣara o si tete nṣe iwosan kiakia o ndin ara wiwu ku. Ṣa fi pa ara wọnu, lakuregbe-ibadi iṣan-ara fifata ati awọn irora lakuregbe miran yio si lọ fagafaga.

ALGESAL jẹ iyanu fun iwosan otutu-agbari pelu

Bere ninu Ile-itaja fun ALGESAL.

Ọgbọn ijinlẹ ti nwọn fi dan ALGESAL wo fihan pe o nwọ ara jinlẹ ni igba mẹta ju awọn egbogi ipara miran lọ.

ALGESAL ni oorun didun, ko si ni abawọn, ko si njo ara. ALGESAL ntura o si nle irora lọ, apo rẹ kọọkan nfun enia ni iwosan atọrun wa.

LO ALGESAL FUN

Lakuregbe-Arinka
Pajapaja
Ara-Gigan
Otutu-Agbari

ALGESAL jẹ egbogi pataki fun awọn osere alagbara pelu

Lakuregbe Ibadi
Lakuregbe Arungun
Alsan wodi-wodi
Lakuregbe Wose-wose





NIGERIAN EXHIBITION
October 1st–22nd
STAND 108

D.P.I. Ltd.,
1 Aerodrome Road,
P.M. Bag 1056, Apapa.

